Imọtaraẹni-nikan maa wa ati awọn àlámọ̀rí kan ti ẹ maa takò wọn" wọn sọ pe: Irẹ ojiṣẹ Ọlọhun, ki ni nnkan ti o maa pa wa láṣẹ? O sọ pe: "Ẹ maa pe ẹtọ ti o jẹ dandan fun yin, ẹ si maa beere lọwọ Ọlọhun nnkan ti o jẹ ti yin

Lati ọdọ ọmọ Mas'ud- ki Ọlọhun yọnu si i- lati ọdọ Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- o sọ pe: "Imọtaraẹni-nikan maa wa ati awọn àlámọ̀rí kan ti ẹ maa takò wọn" wọn sọ pe: Irẹ ojiṣẹ Ọlọhun, ki ni nnkan ti o maa pa wa láṣẹ? O sọ pe: "Ẹ maa pe ẹtọ ti o jẹ dandan fun yin, ẹ si maa beere lọwọ Ọlọhun nnkan ti o jẹ ti yin".

[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pe awọn adari kan maa jẹ lori awọn Musulumi ti wọn ma maa wuwa imọtaraẹninikan pẹlu awọn dukia Musulumi ati eyi ti o yàtọ̀ si i ninu awọn àlámọ̀rí aye, ti wọn ma maa na an gẹgẹ bi wọn ṣe fẹ, ti wọn ma maa kọ fun awọn Musulumi nibi ẹtọ wọn nibẹ. O si maa waye lati ọwọ wọn, awọn àlámọ̀rí kan ti wọn kọ ninu ẹsin. Awọn saabe- ki Ọlọhun yọnu si wọn- beere pé: Ki ni awọn maa ṣe nibi isẹsi yẹn? Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ fun wọn pe didana owo wọn ko lee kọ fun yin lati jẹ ki ẹ kọ nnkan ti o jẹ dandan fun yin si wọn ninu gbigbọ ati itẹle, bi ko ṣe pe ki ẹ ṣe suuru ki ẹ si gbọ́ ki ẹ si tẹle,ẹ ko si gbọdọ fa àlámọ̀rí mọ wọn lọwọ, ki ẹ si beere ẹtọ ti o jẹ ti yin lọdọ Ọlọhun, ati pe ki O tun wọn ṣe, ki O si ti aburu wọn ati abosi wọn lọ.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/3156